U. T. C.
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Akiyesi Pataki**

A fi eyi şe ikede si awọn Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikan ti ko ba fi owo ti o ti je ranşẹ si wa, o pe lejo, ako si ni fi iwe iroh n ranşẹ si enikẹ mọ.

VOL. XI No. 618. LAGOS, SATURDAY, APRIL 4 — APRIL 10, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Iwadi Awon Obinrin Oloja Eko. Oloye Modile Soro.

Oloye Modilẹ ti o jẹ pe, on ni sẹkiteri tabi akọwe fun awọn Oloye ibilẹ Eko (White Cap Chiefs) sọ fun Oluwadi Ọgbẹni Rapson nigbati ẹjọ na yi kan wọn lati sọ si, wipe, awọn ko fi igba kan sọ fun Oloye Lawson pe ọba Adele ran awọn si i ki o jẹki nwọn şe eto orukọ awọn ti o da owo ọja ti nwọn fẹ kọ si Oko Awo ninu Iga Idunganran.

Awọn Ijoye na sọ wipe ninu oşu March 1958 awọn ko sọrọ ohun kan ti o jọ ti ọja kikọ si Oko Awo şugbọn Oloye Lawson ti sọ şiwaju pe, awọn Ijoye ilu wa ba on ninu ile on ni Apapa nwọn si jẹ işẹ ọba Adele fun on pe, die ninu awọn obinrin ọloja ko lati wa sinu Iga Idunganran lati wa gba isọ. Awọn Ijoye dahun pe, irọ ni awọn ko sọrọ ohun ti o jọ bẹ.

Oluwadi ọrọ na tun pe Ọgbẹni Oshodi lati tun wadi ọrọ lẹnu rẹ si i. Ọgbẹni na dahun wipe nitotọ ni on gba Poun mẹfa-mẹfa lọwọ ẹnikọkan awọn obinrin ọloja to mbẹ ni ita Balogun gbogbo owo ti on gba jẹ £216.

Ẹniti o tun sọrọ ni Rafatu Ajikẹ alasọ o sọ pe, on ko pọun mẹfa fun anọ on pe ki o ko la jẹ pe owo isọ ti on niyẹn, on si ri nigbati anọ on na ko owo yi le ọkunrin kan ti on ko tilẹ ba pade ri lọwọ.

Obinrin na Rafatu sọ pe, ọkọ on ti kilọ fun on pe ki on mase sọrọ kan ninu iwadi ọrọ ti o delẹ yi ati pe, on yio da owo na pada fun on.

Ẹnikan ti o tun sọrọ ni Salamọtu Abẹo o wipe ko n şe orukọ gbogbo awọn ti o da owo yi ni a gbọ orukọ wọn ninu iwe iwadi ọrọ yi.

Ọgbẹni M. Lawal ti o je a owe kan nidi oro yi so wipe, ase se ni iwe owo ti nwon se loruko Akanni Doherty pe on lo gba £4,392 a si fi yi i pada pe Akowe ilu lo gba owo na.

Ọgbẹni J. O. Aderemi dahun pe, Onitoju owo (Cashier) ni awonle wipe, on ko le yi oruko na pada nitoripe on ti ko o sile.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Nathaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEWYORK, PARIS HAMBURG.

## Oloye Akintola Lo Si Kano



Oloye S. L. Akintola ti a nwo ninu aworan yi lo lọ pade Ọgbẹni George Ward sẹkiteri agba fun gbogbo awọn ọlọkọ ofurufu labẹ asia Gẹsi nilu Kano.

Akọwe aşiri rẹ Ọgbẹni A. O. Ọrẹdugba ba lọ ati Olori gbogbo awọn alaşẹ ọkọ ofurufu nilẹ Nigeria Ọgbẹni E. R. Coleman.

Bi o ba kuro ni Kano yio lo bẹ agbegbe Katsina wo, yio si gba ibẹ pada wa sile.

## Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina
(Lati Ọwọ Alhaji)

Toba jẹ wipe Eko" Lagos' tabi Kano lo fẹ wọkọ ofurufu ni, awọn ọlọkọ ofurufu yio fi iwe ao di ẹru wa ao ko si mọto, odi Mecca niyẹn. Bi a ba de mecca ako gbọdọ wọle, ao ko ẹru wa si ode ao şe aluwala odi ile Oluwa niyẹn. Bi a ba de ibẹ ao gba bubu Salami wọle. Lẹhina ao yi Ikaba ponigba meje bi a ba yi ile Oluwa po tan ao pọn Ajara Lawadu la ao tun pọn la lẹhinna ao fi omi Sẹmi-Sẹmi wẹ, lẹhinna ao sa safa mariwa nigba meje ao wa fari bi a bade Mecca ao Haya ile ni o. Ile ọdọ Alhaji Bura enia kankan yio san £18 tabi £20 Ile ti rẹ ko jinna si Kaba ile yi wa fun awọn to ba ni owo lọwọ dada. Kosi ibusun nibẹ kosi onjẹ nibẹ. Irẹ fun rara rẹ lo ma wa ibusun ti o ma fi sun ati onjẹ ti o ma jẹ

(Wo yo ku loju ewe kefa)

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS    CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos.    "ELETI - OFE LAGOS"

P. O Box 467    Phone 23370

VOL XI. NO. 618. SATURDAY APRIL 4 - APRIL 10, 1959


# Azikiwe Gbe'rare Sanle

Enia gbe'rarẹ şanlẹ bi akọ warapa" bẹni owe Yoruba mọ-imoni wi, nitoripe "Owe ni ẹşin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu owe ni a fi nwa eyi ni ohun ti o mu wa pa owe oko wosika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa gẹgẹbi irohin ti a ti ngbọ lati nkan bi ọjọ diẹ s'ẹhin lati ile Ariwa, Oke-Ọya nilu awon omo alabusa ti Dr. Azikiwe, Olori ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ti njarunpa kakiri fun ikede idibo ti o mbọ yi.

Gbogbo ọrọ ikede Dokita Azikiwe na dabi igbati awọn ọmọde nşere oşupa ti o jẹ wipe koni ohun meji ti o ngbẹhin ere oşupa rekọja rederede. Awọn enia ti o ba ronu jinlẹ yio gba wipe Dokita Azikiwe ti gbe aja ta o si ti fi owo rẹ ra ọbọ nigbati o jẹ wipe ẹgbẹ N.C.N.C. pelu N.E.P.U. ti ilẹ Gambari ti o jẹ Alatako fun ẹgbẹ Olomi N.P.C. ti akoso ijọba Oke-Ọya mbẹ lọwọ wọn, ni alabaşepọ pẹlu ẹgbẹ ti Azikiwe kio to tun lọ ba awọn ẹgbẹ Olomi N.P.C. sopanpa ti fihan pe ọrọ rẹ ti di rederede ti o ngbẹhin ere oşupa awọn ọmọde.

Nitorina ni a şe fi wosika wa yi ta ẹnyin enia wa ji wipe ki e maşe ka ọrọ rẹ si nkankan, nitoripe agba ofo l'o npariwo.

# Oloye Awolowo So pe Egbe Olope Yio Da Agbegbe Sile.

Jos. Oloye Awolowo so nilu Jos wipe bi ẹ g b ẹ on b a wole ninu ibo ti ao d. loduni awon yio da agbegbe Middle Belt, C.O.R. ati Midwest sile ki asiko ominira wa to-to.

Oro yi ni Dr. Azikiwe gbo ti o si pe Awolowo ni ija wipe, ki o wa la ye wa, ona wo ni yio gba fi da a w o n agbegbe nwonyi sile ki a to gba'Om inira.

Oloye Awolowo dahun pe, Olola Lennox Boyd ti fun on ni ase ti o daju wipe, bi nwon ba dibo tan, t i o n si wole, bi on ba fe, on le da awon agbegbe na sile. Tabi-tabi ko si si, pẹlu a g b a ra Odumare, ori on ni y i o wole ninu ibo ti nwon fe d i na.

Awon enia pataki ti o si je ojogbon ni awon oselu ti o mbe ninu e g be Olopẹ, nitori ti ori won pe, nwon ko je ki asiri na han Dr. Azikiwe titi Dr n a yio fi tun pada wa s e o m o egbe Olope.

# ỌKUNRIN KAN FẸ FI TULASI FẸ IYAWO

**IBADAN Ọmobinrin kan lo nro ẹjọ ni iwaju Adajọ ninu Kotu Ibadan wipe, Gbadebọ ti o jẹ ọkọ iya onile ti on haya, ti nfi gbogbo igba yọ on lẹnu lati fẹ on fi şe aya, şugbọn on ko gba lati fẹ şe oko.**

Ni ojọ kan lo yọ ọbẹ wa ka on mọle wipe ewo ni on nşe on yio gba ifẹ tabi ọna ọrun lo wu on ? Obinrin na sọ pe nigbati on ri ọbẹ lọwọ rẹ, on yara bẹ sode wipe ki o wa pa on sojutaiye ki gbogbo aiye leri

Ọlọpa kan ti o njẹ Laoye sọ wipe, lọjọ ti a wiyi, on ri gbogbo awọn enia ti nwọn sare lọ kiti, kiti si apa ọna Mọkọla on si tẹ le wọn de ibẹ. Nigbati on de ibẹ on ri ọdaran yi ti o ga ọbẹ ti o si dakata le Mero Lọkoja lori, ibe ni on ti yọ si pe kini ohun ti o fẹ şe ?.

Ọdaran na dahun pe, on fẹ pa ni nitori ko nşe oni tabi ana ti on ti npa enia ti on si ti npa enia ti on si ti nmuje, ko si ọlọpa kan ti o le mu on.


Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA, o dara pupọ fun awon ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ọmọtu, ikọ ati orişirişi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni hin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abọ 2 6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.



CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS :-

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWON ONIŞOWO

## THE NIGERIAN GAS CORPORAION LTD.

YIO MA ŞE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAEI DAN

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni şalai muna wa nigb kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

## NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

2, ITAFEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao şe fun yin lọfẹ.



Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials.

PLEASE CONSULT

## Okunowo Brothers

63, Massey Street. (Faji Mrket)

LAGOS, NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.


ọlọju meji dani, o lọ şe ọdẹ bi o ti nlọ şeki-şeki lo şe pẹlu Kiniun, ẹru bàa, o si lerẹ si gbọn loju kanna, titi ti kiniun na fi de ọdọ rẹ, ko le sa o si pa ọkunrin na jẹ.

## Koto Ile Di Omo Akeko Monu'ho

DERBYSHIRE A gbo irohin wipe, omokunrin kan omo ile Eko Oxford College ni o şeşi jin sinu ofin kan eyiti jijin re to egbe un ese.

Awon elegbe re sa ipa ati agbara won lati le fi faa goke, ati nigbati agbara won ko gbe işe na nwon sare lo kesi awon alagba lati wa se iranlowo ijoba pelu ton se gudugudu meje sibe pabo ni nigbehin na, agbo pe okunrin na ku bamubamu sinu ofin na.

Oruko re a ma je Neil Moss o ga to ese mefa, esun meta ige aiya re si fe to ese meji, Awon ojogbon ti o wa fun igbala omo ile eko na sagbara won fun ojo kan, Pabo ni gbogbo re ja si bayi ni okunrin na ba ku gbe.

## KINIUN PA ỌDẸ KAN JẸ

KAFANCHAN. A gbọ wipe awọn Aruno ati awọn Fulani ti nmu mu ẹsun wa nigbagbogbo sọdọ Ijọba wipe awọn ẹranko kiniun wọpọ ni ọdọ wọn Nigbakugba ni nwọn npa malu, ewurẹ ati Kẹtẹkẹtẹ wọn jẹ.

Ijọba ilẹ Hausa si yan iwọn adọta şọja lati lọ rasu awon eranko buruku na. A gbo wipe nwon lọ nwọn ko si ri Kiniun na pa ayafi Koriko.

Ọkunrin agbẹ kan gbe ibọn

## Owo Te Awon Ogboju Olosa

IBADAN Awọn ogboju ọlọşa mẹta nwonyi, Olugbode Ajani, John Kayọde ati Ishọla Laşupọ ni awọn ọlọşa mẹta ti okiki wọn rinlẹ jinijini fun işẹjamba wọn, ti awọn ọlọpa si ti nşe ode wọn ki ọwọ to wọ ba wọn.

Nwọn fi wọn sun ẹsun pe awọn mẹtẹta nwọnyi a ma ko ẹgbẹ ọlọşa kakiri, nwọn ji odidi mọto kan ti ọgọrin apo koko wa ninu rẹ ti nwọn nko lọ si Apapa Iye owo koko ti o wa ninu moto na je ẹdẹgbẹta le legberin Poun (£3,800) oyinbo onişowo G.B Ollivant lo ni awọn ẹru Koko na.

Samuel Ọlakunle ti o nşe dereba moto akeru na, so pe ọna Ikorodu ni on gba ni igbati on de ibuso mẹtadilogota ni awọn ọlọşa mẹta yi ba ko sinu moto taxi, ti nwon si nle on lo titi nwon fi ba on. nwon ni ki on bo sile ninu moto, nwon ju on sile ni nwon goe eru Koko lọ.




## Oyinbo Je Oye Iyalode Onigbagbo

EDE. Ọkan ninu awon Obinrin rere ti Ijo Onitebomi (Baptist Women Missionary Union) ti orukọ rẹ njẹ Neal Convington young. ni ẹniti iṣẹ rere rẹ han s'ode fun gbogbo enia ri, tobẹ ti Alaiyeluwa Timi, Ọba Ẹdẹ fi ranṣẹ pe Obinrin na.

Nigbati o de, Ọba ta lorẹ, o fun ni gele, iborun, ipele iro, buba; o si pe okan ninu awon iyawo rẹ wipe, ki nwon lọ mura fun gege bi aṣa Yoruba, ki nwon si fa a wa si afin Ọba ni biti gbogbo awon oyinbo onisowo ati oyinbo Ijoba pelu enia dudu gbe nreti pipadabọ Obinrin na.

Gbogbo enia patewo, nwon ho ge e nigbati o yọ ninu aso Yoruba. Ọba gbe aga fun lati joko, o si fi oye Iyalode gbogbo awon Onigbagbo ilu Ẹdẹ da lola, o si fi ṣẹkẹ-iyun kọ lọrun.

Iyafin Young di eni ọdun mejidiladọrin. Oye na a mọ o.

## Omo Mahdi Ilu Kadian Ku

KHARTOUM. Irohin kan wa wipe Sir Sayed Abudul Rahman-el Madi, okan ninu awon asiwayu ti o le koko nilu Khartoum ti o je ọkan ninu awon asiwaju ẹsin Islam salaisi nigbati o di eni odun metale ladorin.

Sir Abudu Rahman je okan ọkan ninu awon ọmọ bibi inu Sheihu Mahdi ti o lokiki tobe ti o fi agbara nla re le awon ara ile Egypt kuro ni Sudan niwon adorin ọdun ṣehin. Ninu sare Mahdi ti o wa lati Kadian ni nwon o ṣinku alagba, na si nitori ibe ni a ṣinku baba re si, ni Omduruman.

Awon Ansar, ti Sir Rahman je asiwaju fun, ni ijo Muslim ti o poju nile Sudan. Ijo yi lo pelu awon egbe Umma ti nwon ja fun ominira ile Sudan. Ni oju re ni ile Sudan se gba Ominira ni ọdun 1956 ninu osu January.

## Oriki Awon Ole

Ọle, ọlẹ, ọbun, apa, alata-lori bi dundu ẹlẹranlori bi irẹsi. Ọlẹ ni apa lasan, ko le fi ṣiṣẹ, iya ti o njẹ ọlẹ ko kere, ọlẹ fiya bora sun.

Akukọ kọ, ọlẹ poṣe, o ni ilẹ ma tete yara mọ o, Ki o to ra pala, ki o to yan ho o, ẹni nroko ti de oko, ẹni nre odo ti de odo onranwu ti nranwu, ahun'ṣọ ti nhun aṣọ.

Ọlẹ titori amala ba wọn gbe oku rele Ọyọ, o titori iyan ba wọn gbe odo roko, o nlọ soke odo, o gbe ọmọri odo dani nitori bi yio ba dija, bi yio ba di iyan gigun.

Ebi ko nwọ inu ọlẹ ki ọrọ miran tun wọ. Ọlẹ ko mọ pe, oriṣa bi Ifun ko si ojojumọ lo ngba ẹbọ lọwọ ẹni. Ọlẹ ko mọ mo jẹ ri. Ebi lo nmu ẹnu ọlẹ gbẹ pẹrẹpẹrẹ, o sun silẹ gbalaja loju ọgaja fi ọwọ mẹkẹ, o bẹrẹsi ka igi aja.

Ebi ko jẹki ọlẹ sun, o ngbọn eti papa bi aja ọdẹ. Kiku ọlẹ ko ṣe nkankan aiku ọlẹ ko ṣe ni lore.

Ẹniti o bi ọlẹ ko ri ọmọ bi.

## Arun Lorun -Lorun Tun Bere Loke- Oya

KADUNA. A gbọ irohin wipe ni akoko erun ti oru nmu bi ti asiko yi ni arun lọrunlọrun (Meningistis) ma nsaba bere nile Oke-Ọya nitoripe, oru a ma mu pupọ ni agbegbe ilẹ na ni asiko erun.

Ninu erun ti ọdun ni bi o ti le je wipe arun na ko tete bere sibẹ enia metala ni a gbọ wipe arun na pa si apafọn yanyan.

Iwọn adọsan enia o din ọkan ni awọn ti arun na wa lara rẹ nisisiyi ti nwon si mbẹ ninu ile alaisan.

Ijoba Oke-Oya ko gba gberẹ lọtẹ yi nwon tete mura si itoju awon enia nitori ki arun na ma ba gberan si waju, lasi ani-ani nwon si kapa re.

## MUNISIPA PE ỌBA ADELE LẸJỌ



Awon Minisipa pe oba Adeniji Adele Keji ti o jẹ Baba Ẹgbẹ igbimo Munisipa lẹjo si koto fun gbese owo omi ati atunṣe ilu. Iye owo ti nwon fẹ gba lowo rẹ jẹ £285 14-6d.

Owo na ti nwon fẹ gba jẹ owo omi ti Iga Idunganran ti o jẹ ibugbe Oba Eko.

Nwon fi ọjọ ti nwon o bẹrẹ riro ẹjọ na si oṣu April, 1959.

## BALẸ ILU MAṢIFA ṢALAISI

OGBOMỌṢỌ. Lọjọ ti gbogbo awọn ọmọ Kiriyo nyọ ayọ ojo Ajinde Jesu ni a gbọ pe Oloye Adepoju Adekẹye ti o jẹ Balẹ ilu Maṣifa ni agbegbe Ogbomọṣọ ṣe alaisi.

Ọpọlọpọ awọn enia lo sọ, ti nwon si rohin bi iṣẹ rere Balẹ na ti pọ to. Alagba Balẹ yi d'agba-darugbo to ọmọ ọgọrun odun ki o to faiye silẹ.

## Enia Marun Ndupo Enia Meta

A gbọ wipe ipo awọn enia mẹta ni o wa ninu igbimọ Apapọse tilu Eko awọn enia nwọnyi ni a gbọ pe nwon ndu ipo na mọ ara wọn lọwọ J M J, T O S Benson, Fagbenro Beyioku Ogedengbe Macauley




## Ogun Da Rocha Dijongbon

EKO. A gbọ irohin wipe adajọ kan paṣẹ wipe ki oyinbo Aṣoju gba gbogbo Dukia Ologbe Candido Da-Rocha dani ati gbogbo ẹru ati ohunkohun ti o wa ninu ile Ologbe na ti a npe ni (Water House) ile Olomi, ki o si ko gbogbo awọn ẹru ti o wa nibẹ. A gbọ wipe Dr Ọladele Da Rocha Afodu lo jẹki ọrọ na de kotu

Nwọn sọ pe on lo kọwe si kotu wipe ki nwọn jọwọ ba wọn foju si ọrọ ogun baba wọnyi ki nwọn si ba wọn fi otitẹ tẹ lori ọrọ yi ni Dr. Ọladele bura si bayi wipe

Ninu iwe pinpin ogun ti ologbe Candido Da Rocha ṣe sile ki o to ku, ni ọjọ 23-2-59, a yanmi gẹgẹbi Batansinku ninu iwe na ki Ologbe na to wa ku ni ọjọ 11-3-59. mo bere pe mo fẹ ri iwe ti nwọn fi pin ogun na nitori mo ni ẹtọ lati ni ẹda iwe na lọwọ ati gbogbo nkan ti nwọn ba ninu ile Ologbe na. Mo ti gbidanwo lati ka awọn ẹru na ṣugbọn nwọn ko gba fun mi.

Orukọ awọn enia ti ko gba fun mi na niwọnyi :- Fọlashade Thomas, 18 Campos Street Lagos. Christopher Akinwande Thomas Adegboyega Thoma 18 Campos Sq. Miss Yetunde Thomas Makoko Road E.B 5 Alexanda Da Rocha Yaba, nwọn dẹ awon janduku si mi pe ki nwọn lu mi.

Kere o !

Ati ni orisiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tẹte wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS

MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos

## IRIN AJO O SI MEKA ATI MEDINA

(O bere loju ewe kini)

ṣugbọn ti oluwarẹ koba ni owo lọwọ dada oluwarẹ yio de Mosfala. Ile Ibẹ koju £6. lọ Mosfala yi to 10 minutes Idamẹta busọ kan agogo meji pẹlu abọ oru tiwa ni nwon ki asuba ni Macca 3. 30 a.m. Nitori Ilẹ ti mọ nigbana. Gẹgẹbi moti ni oko iwe yi wipe bi ẹ ba sa safa morila tan ao fari lẹhin eyi ti ẹ ba dele. ao bọ Harami wa sile Oluwarẹ le lo aṣọ to bafẹ ki o ma lo Tawafi ni gbo igba ao wọ moto lati mecca wa si Gidda Iyẹn jẹ maile mẹtalelogoji 43 miles lẹhin na a wa wọ ọkọ ofurufu lati gidda wa si Madina ao lo wakati kan pẹlu abọ ninu ọkọ ofurufu lẹhin ti a ba bọ silẹ ninu ọkọ ofurufu. awọn ọlọkọ ofurufu yio fi Bosi "Bus" wọn gbe yin wa si ilu Medina Iyẹn to mile meji lẹhin ti a ba ilu Medina ao lọ si Mashalashi Mina ao ki Irun ao wa se si ara iboji Anobi Muhammdu.

(Koiti pari)

## Itan Elegbeje Ado

"ISE WA KAN EBORA OSUDUN GIDI GAN WA YI"

Nigbati o wa reti won titi, ti kori won, ohun to wa se nipe o wa can Oji (afẹfẹ nla) si won pe ki o ko gbogbo awon eda enia to ba wa ni tosi ile on, bi Elegbeje-ado ti nro gegẹbi on yio ti se segun re, beni atẹgun nla yi de, o si da jagun yi lamu pupọju, to je wipe ofere bo ohun yo pe kini on wa de ihin, ategun yi si gbe sanlẹ, to jẹ pe o to iṣeju mẹdogun ki o to le dide nilẹ, dide ti o dide, ọwọ lo bọ apo rẹ, ti o si yo ado kan jade. ni o ba bẹrẹ si fi i kakiri, to bẹ ẹ gẹ, ti atẹgun na fi wa du ro, di duro ti o duro. o lo bi iseju marun o wa ni ise to wa se nisisiyi.

O gbera ni ise o fi o fi ese le ọna ile ẹbora Osudun, Osudun kẹ ko mo pe ategun yen ko ti pa eda enia to nyo on lenu. Ọkan rẹ si ti bale gẹgẹbi ti tolotolo. O nmin fin! fin!! fin!!! ko mo pe ẹda enia ju Ẹbora lo lọnakona.

ELEGBEJE-ADO DE ẸNU ỌNA RE

Dide ti jagun de enu ọna, ohun ti o kokọ se nipe, oju ibọn kan sile, to je pe ibon na ro gẹgẹ bi agba ti won nrọ ni Apapa. Gbigbo ti o gbo didun ibọn yi ibẹrubojo ti mu, o nsa sihin, sa sọhun, riri ti jagun ri, ohun ti o se nipe, obusi ẹrin kekeke, o ni ọwọ tẹ o wayi, ẹrin ti Ẹbọra yi gbo, o wo ibi ti o ti gbo erin na o si ri jagun ti o duro bi ogun ọdẹ. Ohun tio kọkọ wi nipe. Ebọra ni ẹ tabi ẹda enia ? jagun dahun pe, ẹda enia ti o ju Ebọra lọ ni.

Ebọra:- Kini o wa de ihin, ọpọn pa ọ [illegible], gbogbo awon ẹda enia egbe rẹ ki ide ibugbe mi, ki o pada si ibugbe rẹ ti o ti wa.

ELELEGBEJE-ADO:- Kini o wi yi ? afinra ni ija ejo, ti o ba yi ehin re pada nisiyi, iya yio si jẹ ọ ni isẹlu akon, tito pe emi yio fi ye ọ pe' ohun ti nko 'le o ti ko gbegi, temi yio si ya o lẹnu, riri ti o ri mi yi moju baba re lo.

EBỌRA ỌSUDUN:- Ha ! o ko'a aye rẹ loni, o fi ẹnu kan baba nla mi bi olori meje se yio seti, ambele bele iwo olori kan ṣoṣo. Baba nla iya yio je o loni gbigbo ti Elegbeje -ado gbo be afinra ni ija ejo, o sunmo gba gba gba a. o si pe ni ija.

## Itumo Ala

Ẹnikeni ti o ba fẹ ki a se itumọ ala rẹ, ki o kọwe si:-
The Joseph, Atumọ-ala.
28, Kosoko Street, Lagos.

1. Ọgbẹni Adẹremi Adesigbin, ti o la ala pe, on ko de oshodi ri, sugbon on woko lo si oshodi. Ala re nso fun ọ pe ki o sọra gidigidi ki arun Jẹdi-jẹdi mase ba ọ ja.

2. Amodu Kekereogun la ala pe on ri awon oyin ti nwon nfo koja lo. Ala re nso fun ọ pe ifa owo kan mbọ wa te ọ lowo laipẹ.

3. Harrison Jẹgẹdẹ la ala pe on ri ẹyin adie lọpọlọpọ. Ala rẹ nsọ fun ọ pe owo nlanla mbọ wa tẹ ọ lọwọ.

4. Yusufu Kadiri la ala pe on ri omi okun t'o nru soke pẹlu igbi rẹ. Ala rẹ nsọ fun ọ pe, ki o sọ owo re ki o ma se na ni inakuna, ki ponju ma ba se ọ bi ọṣẹ ti nṣe oju.

5. Karimu Alade, la ala pe on ri ọkọ oyinbo kan ti o mbo lati ọna okun lokere. Ala rẹ nsọ fun ọ pe, igba rere mbọ wa yi kan o titi ojo meta.

## Oloye Awolowo Nilu Bauchi

Nigbati Oloye Awolowo de ilu Bauchi, awon enia ti o wa pade



rẹ le ni ẹgbẹrun ti okiki Awo ! Awo gbojikan nibiti o gbe mba wọn sọro ti o nse alaye gbogbo ohun ti o ti sapamọ fun won.

## E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN

## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmola bi orisa, akọọlukọ ogun ti ndamọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nbebin l'ore. Iko ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ ọrin o kapa inu wọ, o lu jẹdi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ sẹsẹ, Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o na'gbẹ bo'ra Eyi npa lẹmọ lodiiẹsọ, ọrẹ ikoko, koṣemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o dọga o de ilẹ Hausa, o d'ọba gbogbo Oniṣegun l'o sọ pe lo lẹgbẹ gbogbo ọmọde lo nfẹ ẹ fun ilera

100 KEKERE 2/6d 100 NLA 4s owo ọkọ lọtọ.

THE ẸGBA TRADING ARADAN STORES

13, [illegible] Bridge Street.
P. O. Box 2 Ebute -Meta







Printing & Published By The Union Printing And Publishing Company 28 Kosoko Street, Lagos. P.O. Box 467 Phone 23370